The Hon. ... Chief Secretary to ...

# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI [?] FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO ṢI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

FEB. 1923

VOL. I. No. 31. SATURDAY, FEBRUARY 10, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laila, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO.






Awọn Oyinbo Oniṣowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe oriṣirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranṣẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati oriṣirisi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi ṣi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

Deniga ... Editor.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

*( Macaulay's Household Dispensary.)*

A nti orisirisi ogun Ilera ni Ile-oja yi, to wa ni Popo-nla ( *Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbog yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo ( *Certificated Dispenser.*) lowọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun re jẹ bi idan.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe ( *General Post Office.*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ ( *Telephone* ) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. ỌSUNTOLU, oniṣowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Nkan awọn ọja re ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Ilẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini. ( *Sallen.*)

Ati orisirisi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT MORE IS REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-s e w i n g machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Oniṣowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrénìèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

### KINNI YI D'OTẸ, YE, O D'ỌTẸ!!!

Ọgọrọ Iwe-irohin ni ede wa ni a gbọ pe awọn ẹlomiran npete ati bẹrẹ si ṣe lọdunni: Iyẹn wun wa o; ṣugbọn gẹgẹ bi owe wa kan ti wi "O nbere ibiti ọja ta, o ko be re lọwọ ori"?

### ỌGA NI EUBA.

A ba Ẹni-Ọwọ W. E. EUBA Ọga-Agba Ile-iwe Giga ti Eko yọ gidigidi fun ọdun kẹwa to ti da ina Ile-iwe giga na silẹ, ti o ko lọdunni. Gbere, Oni-kanga-ajimu-ninu-Iwe.

### ADAJỌ ABẸRIN-ṢE FUJA.

O ta si wa leti fẹnrẹn pe Ọgbẹni Ọlọla A. R. PENNINGTON Igbakeji Adajọ Agba yio gba isinmi patapata nigbati o ba lọ sile ni oṣu to mbọ: ni gasikiya, lẹhin iṣẹ-aṣẹ-ku-dorogbo, ara fẹ jojo!

### IJỌ BREADFRUIT ṢE KISA.

A ṣalabapade Isin Akanṣe kan ti awọn Ijọ Oni-dunkun Oyinbo ṣe fun ọdọmọkunrin kan ti a npe ni Ajibade ni gbangan Ile-iwe Ijọ na ni alẹ ọjọ *Thursday* to kọja lati fun ọmọde-mẹsọ na ni iṣiri ati lati dagbere fun u nitori iṣẹ Ọlọrun ti Ijọ na yan si lati lọ ṣe ni Idimu: iṣẹ na ni pẹ ki o mã ṣe Olukọ awọn ọmọde ibẹ ki o si ma wasu fun awọn enia ibẹ pẹlu. Ọgbẹni S. H. Akinwande BAPTIST, Lọya Igbo-fi-dudu-ṣọla ni o jẹ Alaga ipade na, o si ni awọn isangbe lọtun-losi lobinrin, lọkunrin, Alufa Ijọ yi, Ẹni-ọwọ *Archdeacon* Ogunbiyi "fọ 'gi'" ọrọ sisọ ninu ipade na tobẹ ti o mu ori ẹnikẹni wu fun fifi-ara-ẹni-ji fun Iṣẹ-ihinrere, ti a fi ran arakunrin yi. Bẹbẹ ni ka ma ri.

### OJOJO NṢ' OGUN ARA GUN KO LE.

Ilu rọ kẹkẹ lẹnu ọsẹ to kọja fun aisan Ipayẹ Balogun ti a gbọ pe o gb'ọwọ pupọ ni ilu Ajebamidele lọna Ẹpẹ: ọpọ awọn ọmọ rẹ lo ti lọ si ibi ti a wi yi.

### ATABATIBI! ATIBITABA! IHAHA!!!

Igbò-akan-'mọ pa ni Ariya ti awọn SARAKI kan jumọ ṣe fun Ọgbẹni Lọya Adedapọ Kayọde Arepo-pọnda ninu Iwe-ofin, ni gbangba Afari-ogun ni alẹ ana; Balẹ Ọkọ ilu, Ọgbẹni Henry Carr, ni a fi akoso ipade na le lọwọ; Ọgbẹni Adebayọ Ọmọlolu si ṣe bi arirà gẹgẹ bi Akọwe ẹyẹ ati ẹtọ ni alẹ ọjọ na.

### ADUPẸ, A TUN ỌPẸ DA.

A dupẹ lọwọ Ijọ *Catholic* ati Ijọ *Breadfruit* (C.M.S.) fun Akanṣe Adura ti a sọ fun ni pe nwọn ṣe ni ẹnu ọsẹ keji to kọja fun rere Ipade ipejọpọ awọn arakunrin wa ti a ṣe ni ilu Saro lọdunni. Oju ti wa, ẹsẹ wa wọlẹ gẹrẹ lati ri pe gẹgẹ bi ilu Nigeria ti to yi, papa Ilu Eko ti iṣe Olu rẹ, ko si ẹnikan rara ti a yan lati lọ ba awọn ilu mẹtẹta to ku, Saro, Ilu Aganyin ati Gambe jiroro ohun ilọsiwaju iran wa.

### GBANJO "MOTỌ" (*MOTOR*) MEJI TỌRỌ O

Motọ-gbọkankan ti di tọrọ fun t' alọ t' abọ si Ebute-Meta nisisiyi, ko si ẹniti yio wa si "idikọ" awọn kẹkẹ onina wọnyi ni Ita Tinubu, ti ki yio sọ pe, nitotọ, nṣe ni ọpọ iyọ ma nja ọbẹ.

### ILE ẸJỌ AWỌN JURY.

Ni ijọ Monday ijọ karun oṣu yi, ni Ile ẹjọ Ganran ti awọn ọdaran bẹrẹ si iṣẹ.

Ọlọla Adajọ agba RALPH MOLYNEUX COMBE lo ṣe gbogbo awọn ẹjọ na.

Awọn ọdaran marun lo wa ninu ẹjọ na.

EKINI. How-for-do ati Walker.
EKEJI. Jonathan Bọlaji Oṣodi.
EKETA. Jonathan Ọlakitan ati Emanuel Ogunderin
EKERIN. Emanuel A. James.
EKARUN. Ithiel Kọlajọ Doherty.

Ekini a mu u fun ẹṣẹ ọsọlẹ, akọwe ile ẹjọ si bi i lere wipe bi o jẹbi tabi ko jẹbi, awọn mejeji si wipe nwọn ko jẹbi ṣugbọn nigbati nwọn ro ẹjọ wọn wo wọn si fi nwọn silẹ.

Ekeji ni on jẹbi, ẹṣẹ ọsẹlẹ ti nwọn fi sun. Adajọ si ju si ẹwọn ọdun meje pẹlu iṣẹ aṣegan.

Ẹkẹta, ẹṣẹ ti Ijọba fi sun ni wipe wọn ṣe owo fadaka wọn ni awọn ko jẹbi ṣugbọn nigbati a wa idi ẹjọ wọn, a ri wipe wọn jẹbi Adajọ si ju won si ẹwọn ọdun marun ẹnikankan pẹlu iṣẹ aṣegan.

Ẹkẹrin ni ọjọ *Teusday* ijọ kẹfa oṣu ni ọdọmọde ti ko ju ọdun mẹrindilogun lọ, ti o ni kọkọrọ ati ma ṣi apoti iwe ni *Post Office* ti o fi kọkọrọ kan ṣi apoti marundilọgorin o ni on jẹbi ẹsun ti a fi sun on, Adajọ ju si ẹwọn ọdun meje pẹlu iṣẹ aṣegan.

---

## EKO AKETE.

Eko, Saturday February 10, 1923.

---

### EKE L' ỌMỌ ARAIYE, ẸNU WỌN L' ỌFA, ẸNU WỌN L'OJE!!!

Nkan diẹ lo wa ti ki ṣe ẹlẹgẹ gẹgẹbi ọran ilu: (*Pölitics*) ẹnikẹni ti a ba si fi iṣẹ yi ran lati ode-ọrun wa, ni lati jẹ ọlọgbọn-ẹwẹ, onisuru, ati aṣ'aje-masẹ ninu aiya nini ti o to ogun lọtọ.

Pupọ enia lo nro pe ki a ma lọwọ ninu ọran ilu jẹ gbigbe tasi ija si Ijọba: eyi ko ri bẹ rara; nitori awọn ti iru ọrọ yi ko ye lo mu wa lati la alay: rẹ pe ṣiṣe ọran-ilu jẹ iranwọ lọpọlọpọ fun ilu ati fun Ijọba, nitori nipa ọna yi ni awọn enia fi le fi ohun ti o jẹ ẹdun won han Ijọba lọna ọwọ ti yio si mu ki ede gbọn misi-omi-ko-to kuro larin Ilu ati awọn Alaṣẹ rẹ: ọgbọn ati ṣe irufẹ iṣẹ bayi ni lati jẹ ọgbọn ẹlẹ, bibẹkọ, ọran ilu ko ni pẹ ra oluwa rẹ lọwọ bi ẹkọ. Enia le ma ja fun ilu rẹ ni ọna ti o wọ lai jẹ pe Ijọba yan irufẹ ọni bẹ sọju, tabi ki a mu u l' ọta: ọna ti enia ba ṣe eyi ni yio fi oluwarẹ han bi aṣe'lu totọ, ti o si nfi ọwọ Ijọba fun Ijọba, gẹgẹbi Casely Hayford Ọlọla, ti Ilu Aganyin, bi E. H. Cummings, A. J. Sorunke Sawyerr, ati Claudius May, awọn Ọlọla ti ilu Saro, awọn ẹniti oruko wọn ko mu fun ẹnikẹni jake-jado gbogbo agbaiye nitori iṣẹ rere wọn fun ilu wọn: ọna ti a ngba ṣe iṣẹ-ilu lo le mu ibukun tabi egun ba ẹniti o ba nṣe e: "Pẹlẹ sa l' obi, o l'akọ." Ṣugbọn nigbati a boju wo ilu wa nihin nkọ, kila ri? a ri pe awọn to npe ara wọn ni nkan gunmọ ninu ọran-ilu ko to tẹle rara lọ si koto-ọrọ nitori nkan meji kọ, bikoṣe nitori iwa-ada-kandeke wọn, ohun ti a nsọ yi yio ma ro ki ninu irufẹ awọn ẹni bẹ, awọn to jẹ pe bi nwọn ni ki o duro de wọn ni Ereko, ọna Ọba-le-nde ni ao gburo wọn, awọn to jẹ pe bi nwọn jumọ ba ni fi okete san ọgọfa, titi nwọn yio fi gb'ẹhin lọ fi oko kun u, a ko ni mọ mọ, awọn ti oju ki ti lati ma s' ọpa okes'ọpa odo, ti nwọn ki nkọ lati ma ṣe jẹjẹkorodo nipa titan na wọla, awọn to jẹ pe "Afemi" "Afemi" ni nwọn nke ramuram bi kinniun: irufẹ awọn enia wọnyi ni a ni ni igbo ro Eko nisisiyi, ti nwọn ni nwọn nja fun rere ilu! nitotọ, Eke l' ọmọ araiye ẹnu wọn l' ọfa, ẹnu wọn l' oje!!! ẹya irufẹ awọn amu'nuṣika-m'ode-ṣotọ wọnyi lo sọ Eko wa da bi o ti da loni yi.

A ntọrọ pe ki ọjọ na tete yara de, ti ao ri awọn enia bi *Bishop* Johnson Ologbe Arọ-mada'hun-ọkunrin, ati awọn ja-kan-jakan bẹ, ti yio ma ṣe Aṣaju wa, tobẹ ti irẹpọ yio tubọ wa larin wa ati Ijọba wa, fun ilọsiwaju ohun rere gbogbo larin wa.

Oto-gẹ, alu-dundun ki ndarin. Ẹ jẹ ki awọn ọlọkọ-awa wọn l' ẹgba ti a nsọrọ wọn nisisiyi lọ sagbejẹ-mọdi, ki nwọn lọ fi ti ara wọn ṣe ti ara wọn. A ko le ma fi gbogbo ọjọ aiye ẹni jo Agba-ṣina-dan.

Bi owe, bi owe ni a nlu ilu ogidirigbo!!!

---

### ỌBA ALAṢẸ EKEJI ORIṢA. Kabiyesi! ADEMỌLA KEJI ALAKE ỌBA ẸGBA.

Inu wa dun lọpọlọpọ lati ri pe Ọba wa ko fi ọran ọkọ jafara. Imọran rẹ fun awọn ọmọde ni akoko kakoko ti o ba ni anfani ati ba wọn sọrọ ma nṣi ni lori. Ko nye tẹ ẹ

mọ awọn ọmọde leti pe awọn ni yio di oṣelu l'ọla ati pe iru ipo bẹ nfẹ ọgbọn ati oye. A ro pe awọn ọmọ wa ko ni gbagbe pe a nkọ'we de Std. V. a si njade lọ wa 'ṣẹ akọwe ko le mu ilọsiwaju wa fun ilu wa. Ko yẹ ki a ko 'yan awọn iṣẹ bi iṣẹ Agbẹ ṣẹ Gbẹnagbẹna, iṣẹ Agbẹdẹ, ati awọn iṣẹ miran bẹ kere. Ẹni ba si ma tẹle ọna ti iwe, ki o duro re Ṣukuru re bi ọrọ Ṣobọ, ki o kọ ọ de ibiti o to tun. Iya ni abọ ẹkọ nfi jẹ 'nia.

Ọba wa ṣe'un ara! Inu wa dun nigbati a ri iwe ti Ọba wa ati awọn Igbimọ rẹ fi ranṣẹ si olukuluku Ile-ẹkọ ni Abẹokuta ati ẹkun rẹ ni oṣu *November*, lati fi idanwo ọdọdun lọ. O ta si ni leti fẹnrẹn pe owo ti a ti yọda silẹ fun awọn ti ẹbun ba tọ si ninu idanwo ti ọdun yi to pọnwun mẹdọgbọn (£25) a dupẹ lọwọ Mrs. Elliott, Mr. Page ati Mrs. W. R. B. Kuyẹ fun ẹbun ti nwọn pese silẹ ni inawo ara wọn lati fi gbe Ijọba Ẹgba lẹsẹ kabiyesi! Ọba, k' ade pẹ l' ori ki bata pẹ l'ẹsẹ.

---

## ORIN ILẸ WA.

Aṣa lati ma kọ orin ilẹ wa *Native airs* ninu Ile Ọlọrun l'akoko isin kakiri Ijọ enia dudu nba ni l'ara de tobẹ ti a ri wipe o to akoko lati ma toka si aidogba ati alebu ninu awọn orin na ti a nkọ. Lati bi iwọn oṣu mẹta sẹhin ni mo ti nbẹ awọn Ijọ kakiri wo ati Ijọ Iṣọkan gbogbo ẹda lati ṣ'akiyesi oniruru ọna ti awọn Ijọ na fi ngba kọrin ilẹ wa, ati ohun elo orin kikọ gẹgẹbi duru, fere, agogo, konkolo, pandero, ati batakoto ti nwọn fi nkọ awọn orin na. Laisi ani ani, ọpọlọpọ lo mo adun ti o wa ninu kikọ orin ilẹ wa pẹlu ilu ati fere, yala ni ipade ariya tabi ni ipade isin. Nitorina ni mo ṣe tọrọ anfani lọwọ alakoso iwe yi lati le ma sọrọ ninu iwe-irohin rẹ, loṣo-sẹ, nipa orin ilẹ wa. Ki nto bẹrẹ si ṣe eyi, mo tọrọ gafara lọwọ Ijọ kọkan ti nwọn ba nkọ orin ilẹ wa, nitoripe nigbati a ba bẹrẹ si sọ ọ, a le ri eyiti yio gun ni ni kẹsẹ ninu wọn, eyiti o ba si dabi aṣisọ, ngo fi tifẹtifẹ gba atunṣe rẹ. Ireti mi ni pe bi a ba ti mba a lọ, bẹni a o ma ri iyipada ninu awọn orin ilẹ wa ti a nkọ, papa ni Ile isin ọwọ fun Baba Ẹlẹda wa. Mo bẹ gbogbo Ijọ ti nwọn ba nkọ orin ilẹ wa ninu Ile Ọlọrun l'akoko isin pe,

"Ẹ ma ma fi gbigbọ ṣ'aigbọ, Otitọ koro."

Ki Ọlọrun jẹ ka ri iyipada rere fun idagbasoke ijọ ati igbega orilẹ-ede wa. Aṣẹ.

OYENẸYẸ.

---

*"Ajeje ọwọ kan ko gbe 'gba dori awo ni ngbawo ngbọnwọ."*

Si Oniwe "Eko Akete."

O jẹ ohun ti o dun mọ mi lọpọlọpọ lati ri ka ni ninu iwe-irohin rẹ eyiti o jade ni oṣu *December*, nipa iwe kan ti ẹnikan kọ sinu rẹ nipasẹ ilu kekere kan ti a npe ni Ogere ni Ijẹbu Rẹmọ. Eyiti akọle rẹ dun bayi pe "Nasarẹti Ijẹbu Rẹmọ." Nko le ṣalai dupẹ lọwọ iru enia bẹ, ẹniti o ni iru ẹmi ifẹ ati igbeleke fun ilu rẹ. Nitoto o jẹ ohun iwuri fun ni nigbati a gbọ pe pupọ ninu awọn ọmọ Ogere ti de ipo ti o jọju, pupọ wa ninu iṣẹ Ọba, pupọ si wa ni iṣẹ Olukọni, pupọ ẹwẹ si wa ni iṣẹ Alufa, ati pupọ la le ri ni iṣẹ aranṣọ (*Tailoring*) ati iṣẹ agbẹdẹ (*Machinist*) eyi jẹ ohun iwuri fun ni, o si dun lati gbọ gbogbo wọnyi. ṣugbọn mo fẹ bere lọwọ awọn enia wọnyi bi irẹpọ ati ifẹ ba mbẹ larin wọn papa awọn ti o ju wọn lọ; nwọn ha mura wọ nbi ọmọ ilu kanna bi? Nwọn ha fi iwa igberaga ati ati imọtara ẹnibilẹ bi? A ba fẹ ki ogo ilu wa ki o yọ, ẹjẹ ka wo awọn ọpọlọpọ ninu awọn orilẹ ede ti nwọn wa ṣe atipo ni ilu ajeji gẹgẹ bi Eko ati ilu miran to jẹ wipe nwọn ni oriṣiriṣi ẹgbẹ ti nwọn nṣe lati le fi mọ awọn ọpọlọpọ ti o jẹ ọmọ ilu wọn, bi Ijẹṣa, Ẹgba, Ọyọ ati awọn oriṣiriṣi miran ti a ko le darukọ ti nwọn ndu lọnakọna lati gbe ogo ilu wọn dide, nipa eyi ni a ro pe orilẹ-ede le fi lagbara; bi o ti wu ilu kan ki o tobi to tabi ki o kere to, ki awọn enia ti o wa nibẹ si ja fafa ni ẹkọ to, bi ko ba si irẹpọ ati ifẹ larin wọn, orukọ ilu na ko le han, ati pe nwọn ko le ṣe ohun kan ko ni lari; ohun rere kan ko si le ti inu rẹ jade ki a to ke si ẹlomiran ki o ba wa gbe ẹru wa, awa papa ni lati ṣara giri lati kọkọ bẹrẹ gbe ẹru na, dajudaju a mọ pe "Ajeje ọwọ kan ko gbe gba dori awo ni ngbawo n·bọnwọ." Lalai si isowọpọ larin awọn ọmọwe ilu yi ki wọn ṣe ara nwọn ni kan lati fi apẹrẹ rere han awọn Keferi ati Imale eyini ni nipa dida Ẹgbẹ kan pataki kan silẹ ti o jẹ ti gbogbo awọn ọmọwe ilẹ na (*Undernominational Society*) a koi ti le sọ pataki pe ohun rere kan ti ti ibẹ jade.

Nitorina a ke si gbogbo awọn ọmọ Ogere ti o wa ni ile ati ni idalẹ ki nwọn fi imọ ṣọkan lati da nkan yi ro, bi nwọn ba nfẹ be ogo ilẹ wọn yọ. Ki ṣe iwe ti enia mọ nikan lo ngbe ogo ilu rẹ yọ, ṣugbọn ire ti o ba ṣe fun ilu rẹ,ti a o ma ri ohun toka si lẹhin ọla iru ohun ti Ọgbẹni wa Mr. Herbert Macaulay Ajagun-molu ọkunrin, nṣe fun ilu rẹ nisisiyi yẹ ko jẹ apẹrẹ ati ẹkọ fun onikaluku wa ẹlomiran mọ iwe, ṣugbọn ika lo nfi iwe tirẹ ṣe, ẹlomiran si mọ iwe ẹwẹ lati ma fi ṣe ẹjọ kotu lojojumo ni tirẹ, ẹlomiran si mọ iwe tirẹ, o mura nigbakugba lati fi ṣe rere fun ilu ati awọn enia rẹ. Nitorina a ke si gbogbo awọn ọmọ Ogere lat fi ohun ṣọkan ki nwọn ba le dahun lai si ani-'ani nigbati a ba bere pe ohun rere kan ha le ti

Nasareti Ogere jade bi? "Ẹ jade wa wo."
Ẹ jowọ ara, ẹ ba mi kọ orin yi :—

Ara ilu, ara ilu,
Ẹ jẹ ka dọwọ pọ;
K' a le, gb' ogo ilu wa ga,
K' a fi fẹ sọwọ pọ.

*Chorus* :—Pe wọn wale (2)
P' enia dudu wale (2)
Pe wọn wale (2)
P' enia dudu wale.

ỌMỌ-IBILẸ

---

## ỌLỌLA HUTTON MILLS TI ILU AGANYIN.

Ni osẹ ti o kọja a sọ nipa ti ogboni Ọlọla yi, Baba ẹgbẹ *Congress* pe, awọn ẹgbẹ ilu ti Gold Coast (*Aborigines Society*) gba lati gba ẹjọ won ro ni igbimọ ijọba A ri ka ninu iwe irohin ti o de laipẹ yi pe, owo iṣẹ ti awọn ẹgbẹ yi pin jẹ irinwo pọnwun ole ogun (Four hundred guineas) ṣugbọn o da a pada si wọn, pe iṣẹ ilu on ni, on ko fẹ owo rara.

## IFI OHUN ỌGBIN HAN.

Ifi ohun ogbin han, a gburo pe nwọn fẹ ṣe ifi-ohun ọgbin han ni Ibadan ninu oṣu to mbọ, a ni ireti pe eyi yio tubọ mu awọn enia wa kọju si agbẹ ṣiṣẹ rara.

## KABIYESI ỌBA OṢEMỌWE.

O ta si wa ni leti pe, Ọba Oṣemọwe ti Ondo fi owo silẹ lati ran ọmọ mẹta lọ si School giga ti Ondo fun ọdun kan si; eyi jẹ iranlọwọ fun awọn ọmọ ti ori rẹ ba ya, ṣugbọn ti awọn obi rẹ ko ni anfani ati jẹ ki awọn ọmọ wonyi le pari ẹkọ wọn ni kikun. Ọlọrun ko sun ẹmi Ọba siwaju o. *Amin.*

## CHIEF ṢAṢẸRẸ TITUN.

Lehin iku Ṣaṣẹrẹ ni lọlọ yi, a gburo pe Ọba ati awọn Ẹmẹwa ti pimọ pọ, nwọn si ti fi oye yi fun Chief Lomọfẹ. Oye Ṣaṣẹrẹ jẹ ikan ninu agba oye ti Ondo, Chief Lomọfẹ yi ti oruko rẹ papa njẹ SAMUEL AKINLOLA AWOSIKA, jẹ ọmọ Ṣaṣẹrẹ Ayotilẹrẹwa.

Nigbati a si ti fi oye nla fun Chief Lomọfẹ, oye tirẹ si silẹ, awọn onilu si fi aburo rẹ JOSIAH LATUNJI AWOSIKA rọpo rẹ. Ki a to ri oṣu mẹfa si nisisiyi, iye ni gbogbo ilu yio ma ṣe. Njẹ a ki gbogbo wọn ku ipalẹmọ, Oye a mọ'ri o.

## ISIN ATI AṢA ILẸ WA.

Ohun ti mo fẹ sọrọ lori rẹ nisisiyi jẹ eyiti o nipọn pupọ, nko si ro pe ugo le lari rẹ tan ninu ọsẹ yi. Awọn ti mo nfẹ ki nwọn ṣe akiyesi rẹ ni awọn ti Ọlọrun fi jẹ Olori ninu *Church* ti ilẹ wa, eyi ti a npe ni *African Church*. Mo ro pe o to akoko nisisiyi ti awọn *member Church* wọnyi iba ṣe aṣaro ọna wo ni nwọn o fi mu ọwọ ba Ijọ yi nipa ọrọn ti obirin. ọpọlọpọ awọn enia, nigbati nwọn ba ti ṣubu gẹgẹ bi ofin *Church* ti ajeji, nwọn a ko lọ si *Church* ti ibilẹ, bi ẹnipe *Church* ti ibilẹ jẹ eyiti o gba ẹgbin, eyi ko tọ rara, awọn ẹlomiran nwọn a bẹrẹ si obinrin iko jọ lalai tọrọ wọn tabi ki nwọn ṣe ana wọn, eyi ki nṣe aṣa ti enia dudu rara o si yẹ ki *Church* ti ibilẹ kọju ja si iru aṣa wọnyi, ki nwọn ṣe ofin pe ẹniti yio ba jẹ *member* kikun ni lati fi ile rẹ si ọwọ ti o tọ ati ti o yẹ, eyini ni nipa nini obinrin lọna ti o tọ, ki o tọrọ ki o si ṣe ana, iyekiye ti ẹnikẹni ba fẹ, o le ni, ṣugbọn ki o tọrọ, ki o si ṣe ana. Gẹgẹ bi aṣa ilu wa, obinrin ti a ko ba ṣe iwọnyi lori rẹ obinrin lasan ni eyi jẹ, o si yẹ ki awọn *Church* ti ibilẹ fi idi eyi rin lẹ dada.

## ẸGBẸ GBOGBO ENIA DUDU TI ILẸ GẸSI NI IWỌ ORUN AFRICA.

A gburo pe ẹnikẹni ko ni lọ si Saro lati Nigeria si ipade ẹgbẹ yi, Ebute Mẹta ti iba lọ fọn'mu pe bi Eko ko ba lọ, awọn ko ni lọ si ibi kankan. Loju f'emi ifasẹhin ti o buru patapata ni eyi, o si jẹ ohun itiju lọpọlọpọ. Akọwe ẹgbẹ yi nibi ni Dr. Savage; awọn agbalagba npowe pe "Ẹniti o ba ni ki la ma ṣe, l'anṣe e han," ko da mi l'oju bi akọwe ẹgbẹ yi fi ero lu owe yi rara. Ẹnikẹni ti o ba mọ ire ti o le jade lati inu ẹgbẹ yi ko ni da agunla si i, yio sa gbogbo agbara rẹ lati ri pe o lọ siwaju; ẹni kini ti o si yẹ pe ki o sa gbogbo agbara rẹ pe ki oju ma ti wa nibi ni Akọwe ẹgbẹ na.

Awọn kan gbidanwo lẹnu oṣu melo sẹhin lati tun ẹgbẹ yi ṣe, ki o le mulẹ dada, nwọn tẹ iwe si gbogbo ọmọ ẹgbẹ, nwọn si yan awọn ti yio ma ṣiṣẹ lo ninu ẹgbẹ yi, nwọn kọ orukọ won sinu iwe na, nwọn si fi ọjọ si ti nwọn o pade lati fi aṣẹ si orukọ ti o wa ninu iwe, tabi ti nwọn ko ba si fẹ awọn yẹn, ki nwọn yan ẹlomiran. Nigbati nwọn de ajọ nkọ, Akọwe ẹgbẹ pẹlu awọn kan ni eyiti nwọn ṣe yi ko dara, nitorina nwọn ba ajọ ọjọ yi jẹ, nwọn si tun fi ajọ si ijọ miran, ati ijọ na titi di oni oloni, ẹnikẹni ko wa si ajọ. Eyi ha tọ, Akọwe iba ti fi aye silẹ ki nwọn tun ẹgbẹ yi ṣe, oju ki ba ti ti wa bayi loni lo'ju gbogbo agbaiye, "Ẹtẹ awo sa l'ẹtẹ ogbẹri."

Ni eyiti awọn ti o nṣe ẹgbẹ yi ja tilẹ bayi, awọn agbalagba ko ba ni dide si i, awọn oyinbo npe aṣa kan ni "*Conp det at*" eyini ni, nwọn a fi

agbara gba ipo lọwọ ẹniti ko ba jẹ ki ẹgbẹ lọ dada, o yẹ ki awọn *member* ẹgbẹ yi dide fun ara wọn, ki nwọn pe apejọ, ki nwọn fi agbara fi isinmi fun awọn oloye wọn, ki nwọn si tun ẹgbẹ yi ṣe.

FANOKUN,

---

## ADIẸ.

Pupọ ninu wa ni ima sọ pe "adiẹ to ṣu ti ko tọ ara rẹ lo wa" toto, o. Ṣugbọn mo bere, kini ṣe ti adiẹ ki fi tọ? Ẹ jọwọ ẹ maṣe sọ tabi ro pe mo fẹ sọrọ alufaṣa rara, ọrọ lo mu bẹ lọwọ. Ẹnikan sọ pe "gbogbo ẹiyẹ da owo jọ nigba kan, nwọn pọn ọti. Nigbati gbogbo nwọn pe biba lati mu ọti yi, awọn ẹiyẹ yoku ti nmu u tọ o wa kan adiẹ, nigbati o tọ ọ wo, o ri pe o dun pupọ, nijọ na lo ti bura pe lai on ki yio tọ mọ, ki on ma ba tọ ọti didun ti a fi owo iyebiye pọn danu! adiẹ le mu omi, ṣugbọn ko jẹ tọ ọ danu, wọn le fi sọ asọdun ṣugbọn ọkan daju ṣa, pe igbẹ adiẹ ni a ko nilẹ, a ko gba itọ wọn ri!!

2 Nigbati enia ba wa ti o jẹ alaifi nkan pe, o dabi ki enia da egbo ki o maṣe wẹ ẹ, ki o fi silẹ ki o ma kẹ, ko tọ onişegun lọ, nwọn wi fun u titi, ko gbọ, ede ti a nsọ si iru ẹni bẹ ni pe, iwọ lo mọ, ara rẹ lo wa "adiẹ to ṣu ti ko tọ ara rẹ lo wa." Eyi ko fihan nihin pe adiẹ moju owo, eyiti a kọ sọ ṣaju lo jọ bẹ, ṣugbọn nihin, a lo ede to fihan pe adiẹ de nkan mọra. Ẹniti a pe lẹjọ to gba ilu sẹhin, ti njo, ko de nkan mọ'ra bẹ?

3 "Bi adiẹ ba mu omi, a juba Ọlọrun." Sa wo adiẹ, o yatọ si pẹpẹiyẹ, bo ba ti mu omi a gbe ẹnu soke pe "Ọlọrun, mo dupẹ o." Bi ko tilẹ le sọrọ, ko ha jọ bẹ bi o? Ko dojuti awa enia bi? Pupọ ninu wa ni ugba ibukun ati ore Ọlọrun, ṣugbọn a ma ngbagbe lati woke, tabi lati dupẹ lọwọ Olore wa, a ma nro pe ọgbọn inu ati mimọṣe wa ni ohun gbogbo fi ngun fun wa. Nigba pupọ a ki tilẹ ranti pe a ni lati "fi inu didun yin Oluwa Olore" pẹlu. "Ẹniti a ṣe lore ti ko dupẹ, o dabi igbati ọlọṣa ko ni ni ẹru." Awọn Oyinbo gbọn ju wa lọ pupọ, bi nwọn yio ran ọ nişẹ, ti o ṣe aṣe fẹnu gbunlẹ bayi, o ma gbọ "Thank you" Tẹnki ọ". Si ṣe wọn lore, botiwu ki o kere to, nwọn ko jẹ ma sọ pe "Tẹnki ọ", O ha dara ki a ṣe wa lore tan ki a si yipakọ si olore wa, ki a si ma lọ tu-u-u bi ewurẹ gbe iyọ? O yẹ ki awọn obi ma fi kọ ọmọ wọn lati ma dupẹ fun ore yowu ti a ba ṣe fun wọn. Pupọ nfi kọ wọn, ọpọlọpọ ko mọ, nwọn ki si ṣe e. Bi o ko ba mọ ri, wo adiẹ, si kọgbọn lara rẹ. "Otitọ ọrọ a ma koro."

4 Tani ninu wa ti o ti ri adiẹ ti ko ye ri o? mo gbọ, mo si ri pe adiẹ miran ki mọ ọmọ 'toju, ṣugbọn pe ko ye ri, nko ri i ri! bi o ṣe horo meji pere yio ye. Tun gba ọkan si i. Adiẹ kan ko ye ẹyin dudu ki ngo ri i ri, bẹni a si ma pa ọmọ to dudu janjan! O ko ri iṣẹ Edumare bayi? Bi a sọ pe ki a ma sọ iyoku, yio pọju, eyiyi na to. Bi o ba ri adiẹ, ranti pe o moju owo pupọ, ki fowo ṣofo, ranti pe o nkoni lati more ki a si ma dupẹ, ranti pe o ni ẹmi ifarada pupọ, wo bi iti pẹ lori ẹyin to! ranti bi Ọlọrun ti nfi ẹyin rẹ fi agbara Rẹ han.

---

## IDARAYA AWỌN ỌMỌDE.

Orukọ awọn ọmọde to gba ẹbun na ni iwọnyi Ẹbun Ekinni Master Albert Ọbafunmilayọ Coker 5/- 33, Princes Street, Lagos. Ẹbun Ekeji Master James I. Fọlaranmi 2/-6 12, Omididun Street Lagos. Gbogbo iwe ti a ri gba ko ju ogun lọ; awọn mẹrin kan kọ esi ṣọwọ lai fi tọrọ-tọrọ si, nitorina a ko bu iwe wọn wo.

Ki awọn ọmọde ti nwọn jagunmolu yi wa gba ẹbun nwọn ni *Office* wa ni agogo mẹrin ijọ Wednesday ọsẹ to mbọ. A ba nwọn yọ.

JIJA ALỌ NA NI IWỌNYI.

1. Ẹṣin, 2. Omi, 3. Ebi, 4. Ọsan, 5. Owu ati Irin pipọn Alagbẹdẹ, 6. Ẹyin, 7. Ọgẹdẹ ati ọmọ rẹ ti a bẹ lori iya rẹ, 8. Iyọ, Epo, Ẹfọ, 9. Idi ẹnyin, 10. Ẹra, 11. Aro, 12. Ọpẹ.

A o tun tẹ Alọ titun miran sinu iwe Irohin yi lọsẹ to mbọ. Ki awọn to gba ẹbun yi şi sinmi ọsẹ meji na.

(Editor—Eko Akete)

## *Open Letters.* No. 18.

TO CELEBRITIES IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

TO THE REV. FATHER SCHMIDT,

Superior, Catholic Mission, Lagos.

Dear Father-in-God,

The thanks of the Nigerian Community are due to your Church for the Special Prayer which was offered in that SACRED EDIFICE, not long ago for and on behalf of the NATIONAL CONGRESS of BRITISH WEST AFRICA, which has been in its second session in Sierra Leone, since the 28th *ultimo*,

This exemplary act on the part of your ancient Persuasion is warmly commended by all right-thinking persons white and black, in this great Dependency.

Again accept my heartfelt thanks for the Christian spirit evinced by your Mission.

EKO AKETE.

---

"IROHIN KUKURU NIPA AWỌN ẸNITI A FI JẸ OYE DIAKONI ATI ALUFA" NI ỌJỌ ISIMI IJỌ KẸRIN OṢU YI NI ILE ISIN ST. PAUL BREADFRUIT CHURCH.

Ẹniti a fi jẹ Oye Diakoni ni Ọgbẹni Israel Oludọtun Ransome-Kuti; awọn ẹniti a fi jẹ Oye Alufa ni awọn Ẹni-ọwọ Samuel Olusajo Mafe, Emanuel Olabitẹ Ajibọla, Adolphus Ayọade Omideyi, Emanuel Ṣodẹyinde Ogunsanya ati Ogungbe.

Ẹni-ọwọ Bishop I. Oluwọle lo ṣe alakoso isin yi, awọn ẹni-ọwọ to ṣe iranlọwọ ni Ẹni-ọwọ Bishop Melville Jones, Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, Ẹni-ọwọ Evans, Dallimore, J. Pearse, S. M. Abiọdun, J. J. Ransome-Kuti, Gansallo, J. A. Leigh, Johnson, J. A. Cole ati Bolu Payne; nigbati isin yi bẹrẹ ni ago mẹwa, orin 367 "Ẹ ma tẹ siwaju" ni awọn akọrin kọ wọle isin lati ẹnu ọna nla, nipari orin yi ni Ẹni-owọ S. C. Philip ti Ijọ Ondo gori odo lati wasu, ọrọ to fi gba gbogbo Ijọ niyanju ati awọn Ẹni-ọwọ ta fi joye ni ao ri ninu ori kẹfaliwe Matthew ẹsẹ kankanlelọgbọn ati ekejilelọgbọn iwasu na ko gba ju ọgbọn iṣẹju lọ, lẹhin eyi ni Ẹni-ọwọ Gansallo pe orin ogoji, (40) nigbati gbogbo Ijọ kọ orin yi tan ni Ẹni-ọwọ Archdeacon, Ogunbiyi mu Ẹni-ọwọ Kuti wa si waju Bishop Oluwọle fun ati fi jẹ Oye Diakoni; lẹhin eyi lo mu awọn Ẹni-ọwọ marun yoku wa si iwaju Bishop fun Oye Alufa.

Ẹni-ọwọ Gansallo pe orin ikankandilogoje (139) nipari orin yi ni Ẹni-ọwọ Archdeacon Ogunbiyi wa ka adura *Litany*—Ẹniti oka gbogbo nkan yi lori lai fi ikan pe meji gẹgẹ bi oti nma ṣe ni ijọ mẹjọ-mẹjọ to ba nka *Litany* yi—lẹhin eyi ni Ẹni-ọwọ Bishop Oluwọle ka ofin idapọ onjẹ-alẹ Oluwa, ofin mẹwa; nipari ofin yi ni Ẹni-ọwọ Johnson ka ihinrere ti a kọ lati ori kẹrinla ti Efesu bẹrẹ ni ẹsẹ keje: nipari rẹ ni Ẹni-ọwọ Archdeacon Ogunbiyi mu Ẹni-ọwọ I. O. R. Kuti wa si iwaju Bishop Oluwọle ajiṣefini fun iwe aṣẹ ti o si fi le e ni ọwọ pẹlu ibukun; lẹhin rẹ ni a gba Ẹni-ọwọ Kuti si agbo awọn Alufa ni ibiti o gbe ka *Epistle* ti a kọ ninu *Saint Luke* ori kejila bẹrẹ ni ẹsẹ karundilogoji. Lẹhin na ni Ẹni-ọwọ Bishop Oluwọle gba adura, lẹhin na Ẹni-ọwọ Archdeacon mu awọn Diakoni marun yoku wa si iwaju Bishop Oluwọle lati gbe ọwọ le wọn lori fun fifi wọn jẹ Oye Alufa ati gbogbo awọn Ẹni-ọwọ to wa ṣe iranlọwọ ni nwọn da ọwọ jọ gbe le wọn lori nikankan ti Ẹni-ọwọ Bishop Oluwọle fi ọwọ le wọn lori ati Bibeli kankan ati iwe aṣẹ.

Nipari, Ẹni-ọwọ Gansallo pe orin 391 ati 395, ni awọn agbowo bẹrẹ si owo gba; lẹhin eyi, Bishop Oluwọle pari isin, o si fi ibukun fun gbogbo Ijọ.

Lẹhin ti ogunlọgọ enia jade lọ, awọn ẹniti o le duro fun onjẹ-alẹ Oluwa duro.

Ni isin alẹ, Ẹni-ọwọ ti a fi jẹ Oye Diakoni, Israel Oludọtun Ransome-Kuti lo ṣe isin ni ede Oyinbo ọrọ to fi gba ni ni iyanju, ao ri i ninu ori kini ti *Rom.* bẹrẹ ni ẹsẹ kẹrinla, kẹdogun, ikẹrindilogun ati ikẹtadilogun apa kakan ninu ẹsẹ yi lo mu lati gba enia niyanju, ọrọ rẹ jẹ ọrọ iṣiri pupọ pataki ọrọ rẹ lọ fun iṣẹ titun to ṣẹṣẹ gba.

Ohun kan ta ri tabi eyiti a ṣe akiyesi ni isin alẹ ọjọ yi ni pe ka to ka adura "Ọpẹ fun ohun gbogbo" ni Ẹni-ọwọ Archdeacon Ogunbiyi gba adura pataki fun ipade keji ti awọn Ẹgbẹ Iṣọkan ti gbogbo ilẹ enia dudu, *2nd Session of the National Congress of British West Africa* ti nwọn nṣe ni ilẹ Saro ni iṣẹyi ki Oluwa ko gba adura, ko si pẹlu awọn ẹgbẹ yi ninu ero wọn, ati adura wa ni pe ki Oluwa pẹlu awọn Ẹni-ọwọ ti a fi jẹ Oye, ki Oluwa fi ẹsẹ wọn duro ṣinṣin ninu iṣẹ rere ti nwọn gba yi.

ALAFOJURI.

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia.—Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

## Mogbe tana danu Mogbe miran de.

Ile Egbogi ti a npe ni Iṣẹ Olodumare ti o wa ni ẹgbẹ Iga Oloye Aromirẹ ni Ọbun Eko, kun fun orişirişi awọn Egbogi wọnyi ti o şẹşẹ de :—

Egbogi Kuruna, ati Ọṣẹ rẹ, Egbogi Işaka, Jedijedi, Ela ọmọde, Iba, Ipa ọrẹrẹ ọmọde, Egbogi Ẹda ati Aran Kinişa, Egbogi Inu riru iwaşa, ati fun ọkunrin pẹlu, egbogi ki ara ọkunrin le giri (ko ma ye ọ) ati orişirişi awọn eyiti a ko le darukọ tan.

Sare lọ sibẹ, ki ọlọra tirẹ, ọpọkuọyọku ni, bi o fẹ lori, oma dọwọ rẹ o.

"Arun ma jogun, ndagba si ẹlẹda rẹ.".

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## W'O BI, ẸNIKEJI, OJU L' ỌRỌ WA!,

Maşini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ni owo ọpọku-ọyọku ati ni Ile-iwo orişirişi ọja ti

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,

Onişowo ara Jamani ni
Ita 7, Labinjọ, leti Ita William

le gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to şẹşẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-ẹlẹ-gere BICYCLE
Awo Abọmafa ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbọ rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kotu, l' Eko.

## OGUN BURU ILU KO DUN.

O jẹ ohun ibanujẹ gidigidi fun ni lati sọ pe ni arọ ana ni iwọn agogo mẹsan, ni Garan Kotu awọn *Jury* Adajọ Agba SIR RALPH COMBE da Ọgbẹni ITHIEL KỌLAJỌ DOHERTY lẹbi Ẹjọ ti Ọba nba ro pe o ji Ẹgbẹfa pọnwun o le pọnwun merindilogun şile mẹta ati sisi (£1,216 3 6) owo Ọgbẹni kan ti a npe ni Al Hassa Dan Tata. Adajọ na si ju si ẹwọn ọdun kan-abọ pẹlu işẹ-aşegan.

Kẹkẹ p'ohun m'awoko lẹnu ni arọ ana, gbukẹ na ba gbogbo enia labo tobẹ ti olukuluku fi nsọ pe a ko gbọ iru eyi ri, pe Lọya w'ẹwọn. Ninu gbogbo ayida-yida aiye. ati igbi wahala gbogbo Oluwa rere gba wa.

## KERE O! KERE O!!

A fẹ ki gbogbo enia mọ pe a ko lọwọ rara ninu Iwe-irohin ọsọsẹ to şẹşẹ jade ni ọjọ *Wednesday* ọsẹ yi ti o njẹ "Eleti-Ọfẹ" yi ti Ọgbẹni E. A. Akitan nşe nis isiyi.

Ọgọrọ awọn Ọrẹ wa ti nwọn ri iwe-irohin yi şebi tiwa tun ni gẹgẹbi a ti gbọ lẹnu wọn, eyi ko ri bẹ rara, EKO AKETE NIKAN ni Iwe-irohin ọsọsẹ ti wa. A ko si ni nkankan pẹlu iwe-irohin "Eleti-ọfẹ." Ko yẹ ki owo fun owo l' ọrun.

## IMPORTANT TO THE PUBLIC.

As it has come to our hearing that some friends who, on seeing Mr. E. A. Akitan's new Weekly Newspaper "Eleti Ofe" which was published on Wednesday last, are under the impression that we are connected with the paper, this therefore serves to disabuse the minds of all and sundry of our NON-CONNECTION with same, either directly or indirectly.

ED. "EKO AKETE."

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wonyi. (MORNING)

Masses Isin Aro,

6.30 7.30 8.309.30
7.30 8.30 9.3010.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon. T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | -St. Peter's (Alapako) | Rev J A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | —Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev S J Gansallo |
| 9 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J A Leigh |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A N Cole |
| 7 p.m. | | Rev. J. C Cole |
| 10 30 a.m. | Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. J. F. Kuleji |
| 7 p.m. | | Rev. J. A Angus |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | E E Ajọṣe |
| 7 p.m. | | Rev. D A Beckley |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | —Jehovah Shalom | Bro. J. A. Ọlaleyẹ |
| 7 p.m. | | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. W. Bara |
| 6.30 p.m. | | Bro. J. B. Coker |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Rev. E. A. Williams |
| 4.30 p.m. | | Bro. O. Ajayi |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Bro. S. M. Phillips |
| 4 p.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |

EBENEZER (BAPTIST)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | | Bro. J. Bandele |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. Arinọla Ibaru |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rev. H. A. Lewis

---

## OLD FRANCISCANS.

### TEACHER BEECROFT PRESENTATION FUND.

As a mark of gratitude and appreciation a Movement is on foot in the Catholic Community in honour of Mr. W. S. Beecroft's retirement from St. Francis Xavier's School after nearly forty years' connexion.

A committee of the Old Boys, approved and supported by the Catholic Community had been formed to manage the movement.

For a return worthy of the man and creditable to the Old Boys of the School all Past Pupil in Town and abroad are earnestly requested to subscribe liberally to the Fund of which Mr. S. A. Cardozo, LegalOffice, Lagos is the Treasurer.

The proposals at present are :—

1. Address with a very "fat" purse
2. Presentation of 2 Enlarged Photographs
3. Founding of Beecroft's Scholarship.

---

"VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 12 Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBE.

*General Trader*

## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"


## SOMETHING TO YOUR TASTE.

MR. J. D. OLAYAITA, Painting Contractor and General Decorator is prepared to undertaken all paint-works of every description to the entire satisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work: has worked for many important European Firms in town notably, the Firm of P. Z. and also the local P. W. D.

Terms reasonable.
For particulars,
Apply at 16, Mọgaji Lane, Ẹpẹtẹdo.
A trial will convince you.

## ỌMỌ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"
Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,
Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,
Ihin ko to afojuba
A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neuiasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store — VIDAL. R. COLE
P. O. Box 201; 109 Broad Street Lagos

## Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

ni wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko
Ohun a jẹ lo mba ni lọ.


## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti a polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## IGBẸ L' OWO WA.

### EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọwọ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Idapọ-Owo (Niger Co., C. W. Ş., McIver, African Eastern Trading Comporation, Judgen Colonial, Products, John Walkden.)
£11 10 de £12, fun *ton* kan

| | |
|---|---|
| Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) | bakanna. |
| Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) | do. |
| Miller | do. |

### EPO.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ ọyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £24 de £26 fun *ton* kan bakanna


## PAGIDARI!

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wabi-wọsi ohun elo, fun Ọmọge ati Ọmọde-m'ẹṣọ ti o si nta ni ita oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile ọja na, ti a nşe Gbajamọ fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi tọrọ.

Egbogi orişi-rişi iwosan oniruuru aisan, Ipara olo-orun, ati agbọrun Jigin-oju, ati nkan meremere pọ to wọbu nibẹ.

Ikan-o-jọkan irin iṣẹ ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibẹ ni ọpọku yọku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan pọ nibẹ bere ohun-ko-hun ti o ba nfẹ yio pese rẹ fun ọ.

O ngbero laipẹ, lati şi ile Erọ Idan Awoşeju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibẹ
Irohin ko to afojuba.

*P O. Box 159* — *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe sọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ

108, Moloney Bridge St.

P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.

*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

29, Oripasan Lane,

King's Quarter, Isale Eko,

Lagos, Nigeria.

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experience in Dirty Window Cleaning, Changing of Plan Window to any colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or white washing of wall to any kind as Distemper colour etc., Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Vasdia and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint House and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogaji,**
*General Manager.*

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

---

AWON ẸGBẸ OYINBO ONISOWỌ TI A NPE NI

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18, GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn na nranşẹ oja fun enikẹni to ba fẹ' ibaşẹ ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Ẹpo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria.*

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Forto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsị, niti *German* tabi niti *French.*

Oruko adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD., 8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.